OJU OLE RE OLE! OWO OLOWO OLE!

AWOGBA
Omode fun
Giri, Eyi,
Mihn-ehin,
Owo,
Ra Tire Ni
Ile Egbori
— 158 —
Oladunni
Okebola,
Ibadan.
116, Great
Bridge St.,
LAGOS

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe,
Brown, Black & Grey
Before 50/- Now 42/6d
Obtainable at :-
A. B. AKINYEMI
10A Moloney Bridge St,
LAGOS.

VOL. VIII No. 456. ELETI - OFẸ LAGOS, SATURDAY, FEBRUARY 25, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)

## Oju Ole Re Ole! Owo Olowo Ole!

L'owurọ kutu hai mọju ọjọ Alamisi ọsẹ yi ni ariwo nla gee, l'ọna Isalẹgangan mọ adugbo Okepopo, ni gbogbo rẹ nho gee wipe "Oju ole re, ole, Owo olowo, ole, aṣọ alaṣọ ole, ẹran ẹlẹran ole.

Kini a ma ri larin awọn ogo-wẹrẹ ọmọ-ekee bi ẹgbagbeje janduku enia, ọkunrin wọ nkuku, wọ nkọkọ, aja'le-Onile bo tirẹ lẹhin.

Nwọn ni Tijani Ọṣọlo ni ẹlẹgiri na lọ ji ẹran ewure kan pẹlu awọn aṣọ bi irepe, bi odidi ti awọn gb'ewosiro ọmọ wẹrẹ awọnyi nki'gbe lẹhin rẹ gẹgẹbi orin ti akọ s'eke yi.

Bi ẹ ba foju ri Tijani Ọṣọlẹ yi lọjọ na, ako mọ ohun ti a le fi we, nitoripe o fi okun bọ Ewure lọrun, o so okun na mọ idi ara rẹ, o si wa mu awọn aṣọ ti o ji ko wọnye, o fi wọn gbanu-gbaiya bi ẹlẹgun Ṣongo ọrẹ ko wọ lẹjọ yi.

Oju jangun ọkunrin na pọn binako; o wa gba alejo wẹwẹ s'ẹhin, ohun ti o ya wa l'ẹnu ni wipe ako ri ẹniti ọknarin buruku ja l'ole, ako si mọ ọna ti awọn ọmọ wẹwẹ gba de ẹhin rẹ, a ri wipe o fi wọn nturuku kiri lasan ṣa ni.

Alaini itiju enia ma pọ l'aiye o, ẹnyin ara wa.

## Abo "Gorsuch" Re O Ebora

OWO BODE GOKE, EPE! ỌMỌ NYIN A JẸ NIBẸ

On niyi o, abọ ẹkunwo ojojumọ fun awọn oṣiṣẹ niyi. Owo Bode goke o le konka gbogbo awọn ẹniti ko gba ẹkunwo lọ ma san, atọmọ-dọmọ rẹ pẹlu yio sau.

Lati ọjọ 24th oṣu Feb. 1956 lowo Bode ti goke ti o si kamama, lori gbogbo awọn ẹru ti o nti ilẹ okere wa lọna okun. Diẹ ninu awọn ẹru na ti o gbe owo lori ni Bode ni awọn nwọnyi Oti gini, Brandi, Wisiki, Beer Stout, Wine.
Ewu Ṣọti, Singlẹti, Bata, Kẹkẹ Basikulu, Iṣana, Mọto, Motor Cycle, Lafinda Olorun didun Ewe taba toyinbo Agbeji Agborun, Aburasida Ẹja Panla nikan loku ti ko gbowo lori.

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited.

Ọna tara ti enia legba lati
di onisowo nilẹ Nigeria wa,
ni ile Ifowopamọsi ti NATIONAL BANK
Enikẹni ti o ba fẹ kan ogunlọgọ
aimọye awọn onisowo ilẹ Nigeria lara,
yala lati ma ta ọja fun wọn ni,
tabi lati ma ra awọn ohun ọgbin ilẹ wa,
ki o lọ si NATIONAL BANK

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 308, Lagos.
AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

## Opa Adehun Titun Fun Igbimo Eko



MR. J. E. STAPLEY

Ọpa adehun titun ti awọn igbimọ nla ti Ọba Ilu Oyinbo fi ranṣẹ si igbimọ nla ti Eko, House of Representative ni eyiti a nwo ti Ọkunrin kan gbe dani ninu aworan yi. Adehun na ni wipe ohunkohun ti nwọn ba sọ ni igbimọ na, Ọba Oyinbo lọwọ si.

Ẹniti o ṣe tabi ti o rọ ọpa adehun na lo gbee dani ti a nwo ni, orukọ rẹ ni Ọgbẹni J.E. Stapley.

Ẹsẹ mẹrin ni ọpa na fi gun, aworan ade St. Edward lo mbẹ lori rẹ. Ninu ade na ni a fi otitẹ adehun na si Wura ati Fadaka ni a fi ṣiṣẹ ọpa na, awọn nkan ilẹ Nigeria ni a fi sami sibẹ Ori ọpa na dabi eso Koko, lara rẹ si ni ami Ijọba wa.

Aworan awọn ẹranko ilẹ Nigeria ni a fi ṣe ọrun ọpa na lọṣọ nṣe ni a lọ ọpa na ni awọ kubusu gẹgẹbi awọ Odo Ọya ati Odo Binuwẹ.

Ọpa adehun yi jẹ ami ọrẹ larin ilẹ Nigeria ati Ilu Oyinbo Gẹsi ati pe awọn faramọ ofin ilu ati igbimọ.

## Rogbodiyan Be Sile Ni Ikom

A gbọ irohin wipe rogbodiyan kan bẹ silẹ nilu kan ti a npe ni Ikom latari owo ori. Gbadiẹ sin, biya mi ko si, nko ni sio.

Apakan awọn enia na sọ wipe owo ori ti nwọn bu fun wọn lọdun yi pọju, nitorina nwọn ko ni san, awọn miran tilẹ kọ jalẹjalẹ wipe ndao, nwọn ko ni san ẹp nni aladọjọ

Nigbati ọrọ na wa di fami ki nfa ọ to si fẹrẹ dabi ẹni wipe apa ijọba ko ka wọn mọ nwọn ranṣẹ si awọn 999. Bi iṣeju akan nwọn ti dira de, awọn ọlọpa ti o jẹ wipe, nwọn ko ni rin ki wọn ṣonwọ kumọ.

Bi awọn enia na ti foju kan awọn Ọlọpa ninu fila irin pẹlu aiẹ ija lọwọ osi, ati pompo lọwọ ọtun, igbẹ lanfẹ ewe, bẹni awọn adagba-malẹṣ: ba fi ori mọkun.

## Idowu Di Omo Orukan

Ọdọmọkunrin kan ti a npe ni Idowu Salami Ọdu, ẹniti nwọn lu baba rẹ pa ninu igbo kan ti wọn npe ni Owuru ni Ikorodu. Idowu yi ko mọ iya rẹ, nitorina ... kere lo wa ti iya rẹ ... jẹ ... ba ọ ... Ko si mọ ẹnikan ... enia iya tabi ti baba rẹ ... bayi, od ọmọ Orukan. Bi a Idowu ko nṣe ara iko odu, ọmọ lesha nise

Agbẹjọro Ọba bere lọwọ ọmọ na wipe ri bo ni baba rẹ gbe wa ọmọ dahun pẹlu ẹkun wipe o si ko Anu rẹ si ṣe gbogbo enia O sọ wipe Agbẹ ni baba on nṣe o si tun nṣe Aṣode Nigbati ẹkun ọmọ pọ ni adajọ na yẹ ejọ rẹ sigba miran.

## Akodu Ati Chagory Tun Pada Sere Esin

Awọn Ọgbẹni nwọnyi Ade Akodu, A. Chagoury ati Ọgbẹni Ferris George ti nwọn ṣe aṣemaṣe kan ninu ẹgbẹ ẹlẹrẹ ẹṣin ti a si da wọn duro, Awọn mẹtẹta, na ti sujada a si ti gba wọn pada sinu awujọ ẹlẹrẹ ẹṣin nisisiyi.

Alaga ẹgbẹ na, Ọgbẹni J.K. Randle lo bẹbẹ fun igba-pada awọn enia na lati fi ṣe iranti asẹko ti ọba obinrin wa bẹ ilẹ Nigeria wo.

Gbogbo ọmọ ẹgbẹ si gba tiẹ-tiẹ lati gba awọn enia na pada.

## Awolowo Yio Rin Ile Aiye Lo Fun Ilosiwaju



AWOLOWO

Irohin kan wa wipe Ọlọla Chief Awolọwọ ati Ọgbẹni Okorodudu Aṣoju nilu Ọba Ọgbẹni Chief C.D. Akran Alaga ẹgbẹ W.R.P.D.B. Ọgbẹni R.A. Croft; at Ọgbẹni G. Thomas, aṣoju awọn Oniṣowo nilu Ọba, ngbaradi nisisiyi lati rin ilẹ aiye lọ fun ilọsiwaju ilẹ Yoruba a si gbọ wipe awọn ilu ti wọn o de nilu Ọba Gesi, Ilẹ Amẹrika, ilẹ Aguda (Italy) Ilẹ Kanada Ilẹ Japan, ati awọn ilẹ



C. D. AKRAN

miran.

Ohun ti nwọn nlọ ṣe ni wipe Lati jẹki araiye mọ awọn ohun ti Ijọba Iwọ orun nfẹ ilọsiwaju wọn ki wọn si le mọ iru iranlọwọ ti nwọn le ri ni ilu okere

## Oba Ilu Gesi Dupe Lowo Awon Sanmori Eko

Ọrọ yinni-yinni ki ẹni le ṣe omiran Kabiyesi, ọlọla ọba Obinrin ilu Oyinbo ti fi aṣẹ fun ọlọla Gomina Agba tilu Eko wipe, ki o ba on dupe fun gbogbo awọn sanmọri ilu Eko ti nwọn lọwọ ninu iyẹsi on lasẹko ti o nwa bẹ ilẹ Nigeria wo.

Nitorina, fun iru iṣẹ ribi ribi ti o ṣe gẹgẹbi Oniwe Irohin, oruko rẹ jẹ ọkan pataki ti a fi siwaju ijọba lati dupe fun.



Councillor TAJU THOMPSON

Aworan ti a nwo yi ni ti Ọgbẹni Taju Thompson Olotu iwe Irohin Eleti-Ọfẹ o jẹ ọkan ninu awọn Sanmọri Eko ti Ọba Oyinbo dupe lọwọ rẹ.

## Ojo Owuro Lo Mbi Olowo Ninu Olowo Gelete Iwofa Si Gelete


**MECCA PILGRIMAGE 1956**

KANO to JEDDAH

FARE £125.0.0 RETURN

PILGRIM DUES & TAXES £6.6.0

Comfortable four engined D.C. 4 Skymaster Aircraft

Make your booking early at any office of WAAC or appointed agents

WEST AFRICAN AIRWAYS CORPORATION

## Ikomo Dun O Larinrin

ADJAME Ni ọjọ kokanla oṣu January 1956, ni Oluwa fi ọmọkunrin lantiланti kan ta Ọgbẹni wa Joseph O. Alabi (aṣoju Eleti - Ọfẹ ni ilu Adjame) ati iya ọmọ Maria Oyinlade lọrẹ, lati ọjọ ibi ọmọ yi titi di ọjọ isami ni baba ati iya ọmọde yi ti npese jijẹ ati mimu fun awọn aladugbo, papa julọ awọn obinrin alaba ṣọyẹ.

Nigbati o di ọjọ kejidilogun oṣu n a ti iṣe ọjọ ikomọ ni dede agogo mejọ owurọ ni ẹsẹ awọn Onigbagbọ gbogbo pe si ile baba ọmọ yi lati sọ oruko ọmọ. Oruko ọmọ na, a ma jẹ George Oyeniran Alabi ki Oluwa ba wa wo ọmọ na fun Ọla ati Ogo Rẹ Amin.

Die ninu awọn gbajumọ ti nwọn wa si bi isọmo loruko na niwonyi:- Yesufu Oluwọye, Emmanuel Alabi, David Oyewọle Jacob Lawore, Daniel Oluwọye, John Gbonro, Samuel Toki, David Amao Aladji Salami Ọyọlọla, Alufa Sunmaila, James Bamidele, Yesufu Oyeniran John Ọlawọyin, Micheal Adeyeye, Emmanuel Ọlaaiyi, Yesufu Akinpẹlu Salawu Ọmọgboye, Aṣafa Liasu, Raji Moṣebolatan, Oseni Taiye, Shitu Adigun, S. P. Ọmọdele J. Atanda. Ki Oluwa pin adun kari gbogbo wa o. Amin.

Owo ẹbun ti nwọn fun baba ọmọ ni ọjọ na jẹ £30 9/- 3d.

## Awon Ajo Igbimo Ilu Oyinbo

### YAN AWỌN ENIA TI YIO WA BẸ ILU WA WO

A gbọ wipe awọn enia pataki pataki bi mejọ ni awọn Igbimọ Ilu Oyinbo yan ti yio wa bẹ ilu wa wo. Gẹgẹbi a ti gbọ ni wipe awọn ti a yan na yio fi ilu Oyinbo silẹ ni ọjọ Kejilelogun oṣu February yi wa si Eko, Ọgbẹn Walter Elliot ni yio jẹ akonijẹ wọn.

Nigbati nwọn ba de si Eko, nwọn yio fun ile Igbimọ nla Eko Eko (House of Representatives) ni ọpa kan (Mace) ni ọjọ kẹdọgbọn oṣu February yi. nigbati Igbimọ na yio ṣe ipade.

Lẹhinna ni Ọgbẹni Walter Elliot yio fo pada lọ silu London nigbana ni Ọgbẹni Greech Jones yio pada sipo akonijẹ fun awọn olubẹwo yoku.

(Wo yoku loju ewe kerin)


## Ma Wo Sinima Ninu Ile Re



Ẹrọ Sinima To Gbadun Gbogbo Irin'ṣẹ Re Ni O Ye Koro Pẹlu Itanṣan Ina To Mọlẹ O Nfi Atupa Lẹtiriki Ṣiṣẹ. Ma Gbadun Sinima Ati awọn Irawọ Rẹ Ti Yio Ma Yi, Yio Ma Dara Ati Ijo Pẹlu Agbara Ayika 35 mm. Ao Fi Ile Rẹ To GUN Ni ẸSẸ 55. Ranṣẹ L'ọ Fẹ.

Eyi Ti O Dara Julọ £3. 0. 0. Awọn Ile Rẹ Nikan Elọsẹ Mẹfa 6/ E Fi Owo Ranṣẹ Patapata. Ko Si Awin.
NATIONAL NOVELTIES (205), BULANSHARA, (U.P.) INDIA


## Notice to Building Contractors

### WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

The Board proposes to erect a number of Buildings during the financial year 1956-57.

Contractors wishing to tender for any or all of this work are asked to notify the Secretary, Western Region Production Development Board, Ibadan, by letter not later than noon on Wednesday the 29th of February, 1956.

Replies should include information regarding the experience of the applicant, the extent of his business and should be accompanied by a Banker's Reference.



ỌLỌLA NLA ỌMỌ 'BA'BINRIN MARGARET

Aworan inu iwe wa yi niti Ọlọlanla ọmọ'ba obinrin ti a npe ni Margaret ti iṣe aburo lẹhin fun Ọba obinrin ilu Oyinbo Gẹsi ti o ṣẹṣẹ fi ilu wa Nigeria yi silẹ lẹhin oyinkan ọla abẹwo rẹ to ṣe pẹlu Ọlọlajulọ ayanfẹ ọkọ rẹ wa si ilu Nigeria wa yi.

Ọmọ'ba Margaret lọ ṣe abẹwo ile iṣẹ ẹrọ gbohungbohun ni Amersham nilu Buckinghamshire laipẹ yi.



Aworan inu Iwe wa yi niti Oloye Michael Okorodudu pẹlu iyawo ati awọn ọmọ rẹ nibi ti nwọn ti nta Ludo ninu ile rẹ nilu' Oyinbo.

Aworan yi lati ọwọ osi:- Bisede, Oloye Okorodudu Iyawo rẹ Josephine ati Ladi.

Oloye Okorodudu bẹrẹ iṣẹ rẹ gẹgẹbi aṣoju Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Nigeria ninu oṣu October ti ọdun 1954 nilu Oyinbo, ọkan pataki si ni iṣe ninu ẹbi Olu Warri, Ọba ilu Ṣẹkiri.

Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki O Si Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Aladun Yi

ELETI ỌFE
A-NIU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
29, Yesoko Street Lagos "ELETI - QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL VIII NO. 456 LAGOS, SATURDAY FEB, 25, 1956.

# Iwa Rere Leso Enia

Gbo'gbun akole oke wosika wa ọsẹ yi jẹ owe Yoruba g'okhun na ni a fi ṣe ẹsin ọrọ wa ọsẹ yi ti a fẹ fi si ẹ yio enia wa leti nipa iwa ati iṣe Alaiyeluwa Ọba Obinrin Ilu Gẹsi ti o yẹ ki o jẹ ẹkọ pataki fun wa gẹgẹbi ilu ti o nkpa lati di ọkan ninu awọn ilu Orilẹ-ede Ominira.

Enikẹni ti o ba sorire fi oju ri Alaiyeluwa Ọba'binrin na, laisi aniani, yio jẹri si ọrọ wa wipe eni-aiye efe na fi iwa irẹlẹ ati iwọntu-wọnsi han fun wa gedegbe, ninu gbogbo itẹ rẹ, pataki nipa aṣọ wiwọ fi ṣe ọṣọ ara, isọrọ si enia, ati ki a maa fi ẹrin musẹ pẹlu oju ifẹ si ẹnikẹni ti o mu ki ifẹ rẹ gba ọkan gbogbo enia to fi jẹ wipe bi ki o ma pada lọ si ilu rẹ mọ ni o ri l'oju ọpọlọpọ enia.

EIẸ KI AKO ẸKỌ RERE

Bi o ba ṣe wipe ọkan ninu awọn obinrin ilẹ wa ni Elẹda gbe si aye ti o gbamuṣe diẹ, ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti irufẹ ipo ti Alaiyeluwa wa bi yio ba jade, dajudaju bi enia ba ri, yio fẹrẹ le wipe. golu ni gbogbo aṣọ rẹ, ti yio ko boribọtun de'po ti yio ko abuku ba ẹwa ti Olodumare fi ṣe lọṣọ baiye.

Gbogbo iru iwa amọga ati aṣeleke ẹpọn tọ ajẹ ipa, ti o ti jẹ iwapati ise wa, nigbati ari irufẹ iwa irẹlẹ ati iwọntun-wọnsi ti Alaiyeluwa ọba Obinrin ilu Oyinbo Gẹsi fi han wa yi, o tọ, o si yẹ ki a kọ ẹkọ nipa rẹ.

Iwa irẹlẹ ati Iwọtun-iwọnsi ninu ohun gbogbo l'ode aiye ni ogo enia, nitorina ẹ jẹki a kọ ẹkọ rere nitoripe "Iwa rere l'ẹṣọ enia". Bẹni owe Yoruba wi!



Mr. Stocker

## Mo Ba Ogbeni Stocker Yo Jojo

Laipe yi, nigbati Oba Obinrin tilu Gesi wa be Ile Nigeria wo, okan ninu awon enia ti o sorire ti oba na fi oye Royal Victorian Order da lola ni Ogbeni John Stocker ti o nse oga ni Information Office ni Eko.

## Owo Ife Obinrin

YIO DI OFIN NI GABASI

Ọpọlọpọ awọn enia loti nkebosi ninu iwe Irohin wipe owo Ifẹ obinrin ti ga pupọju nilẹ awọn Ibo. Ni ọdun Esi ni Ijọba ilẹ na yan awọn Igbimọ kan lati lọ se ofintoto nipa owo Ifẹ obinrin

Ninu oṣu March ti a o bọ si yi ni nwọn fẹ gbe ọrọ owo Ifẹ yi lọ siwaju igbimọ House of Assembly lati sọ ọrọ na di ofin nipa iyẹ ti ao ma fẹ Obinrin nilẹ Ibo.

Lẹhin ti ọrọ na ba ti di ofin tan, ẹniti o ba mọ ọ 'ẹwa, tio yan a run ti o ba huwa ti o lodi si ofin yi nigbana ni nwọn o fi tẹtẹ ofin jẹ oluwarẹ yio san adọta pọun tabi ẹwọn oṣu mẹfa.

Awọn ẹgbẹ kan ti a npe ni Osu ti o ti ṣe ofin larin ara wọn wipe ẹnikẹni ti ko nṣe ara ọmọ ẹgbẹ yi, kogbọdọ lọkọ ninu ẹgbẹ Osu tabi ki o laya nibẹ.

Ṣugbọn nisisiyi ofin titun yi yio fi opin si iru aṣa bawọnyi.

## Ikomo Miringindin

Ikomọ, G.A. Maku dun, O miringindin ni ọjọ Alamisi ti iṣe ọjọ keji oṣu Feb 1956, Ọlọrun fi ọmọ ọkunrin kan ta Ọgbẹni G.A. Maku lọrẹ ni ọjọ kẹjọ ti abi Ọmọ na ni awọn Alufa wa sọ ọmọ na ni oruko. Ki ọjọ kẹjọ na to pe gbogbo awọn ọrẹ Ọgbẹni G.A Maku yi gbogbo awọn ti o wa ni ọna idalẹ ni Ajebọ ni ẹgbẹ Ijẹbu Ipẹru ati ile Iffẹ ni garage Ọlọde, gbogbo wọn de si Eko yi, lati wa sọ ọmọ na loruko ati lati wa ba ṣe ẹyẹ ọmọ na.

Larọ ọjọ ti a fẹ ko ọmọ na jade, ẹsẹ awọn ẹbi pe lọkunrin ati lobinrin lọmọde ati lagba nigbati o di ikan bi agogo mẹjọ arọ ni ọjọ na ni awọn Alufa pe jọ si ile ọgbẹni wa G. A. Maku lati sọ ọmọ na loruko Alufa ti o sọ ọmọ na loruko a ma jẹ Alhaji Sanni jẹjẹ Alhaji Salimọnu ati Alfa Bọdunrin ati Alhaji Owu ati gbogbo awọn ọmọ wa.

Oruko ọmọ na amajẹ ABUDULAI FATAYI ỌLAYIWỌLA MAKU baba ọmọ na fi ijẹ mimu tewọn lọrun. Awọn alabaṣeye ọjọ na ni Ọgbẹni wa Y. S. Bankolẹ Chairman Egbẹ Kobinu ẹnikan ọmọ Oke Ọdẹ to wani eko ati gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ati awọn ọrẹ baba ọmọ ti wọn jẹ ọmọ eko Ha! modupe lọwọ awọn ọmọ Oke-Ọdẹ lọjọ na, wọn ṣe inawo pupọ.

Emi ni Tiyin,
G. A. MAKU



Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

# IROHIN ILU OYINBO

## Olola - Nla Ti Edinburgh Ti Ise Oko Oba Obinrin Ile Gesi Je Atuko Olokiki

Lati Ọwọ Ọgbẹni FRANK PAGE.

Ninu nan ilẹ Gẹsi, o jẹ akoko ti atukọ kan ti o nṣiṣẹ ninu ọkọ oju omi ti ọba di ọkọ ọba obinrin ilẹ Gẹsi nigbati Elizabeth Keji gun ori itẹ.

Boya nitori iru ẹkọ ati iriri ti oloye ti Edinburgh ni lakoko na ni o fi di onimọran daradara fun iyawo rẹ nisisiyi.

O fẹran agbami pupa, o tilẹ jogun iṣẹ atukọ ni. Baba rẹ agba ọmọ - ọba Louis ti Battenberg ti jẹ oloye pataki ri fun awọn ọkọ oju omi ti ijọba Gẹsi. Aburo Baba rẹ ni o si tun gba ipo yi nisisiyi.

AKOKO OGUN NI AGBAMI OKUN

Lẹhin igbati oloye ti Edinburgh yi kọ ẹkọ nipa bi a ti ṣe ma ṣiṣẹ ninu ilu tan ni Scotland o tẹsiwaju lati lọ kọ ẹkọ ni ile - ẹkọ ti awọn ọmọ'gun ni ibiti a npe ni Britannia Royal Naval College ni Dartmouth. Nibi ni o si ti gba iyi ati ẹye gẹgẹbi akẹkọ ti o dara julọ. Kete ti o bẹrẹ ẹkọ nipa iṣẹ ogagun, o ṣe idanwo, ayọrisi rẹ si wa opọlọpọ awọn olukọ ati akẹkọ yioku lori pupọ.

Ọmọ ọdun mẹkandilogun pere ni nigbati o bọ si agbami okun lati di atukọ ninu ọkọ omi ologun ti a npe ni Ramillies. Nigbati o tun ṣiṣẹ kakiri, a yan lati jẹ ọkan ninu awọn ọga atukọ ninu ọkọ omi ologun ti a npe ni Valiant ni agbami okun Mediterranean. Ninu ogun ti won ja ni Cape Matapan ni ọdun mẹdọgbọn sẹhin, o jẹ ọkan ninu awọn atukọ ti wọn yan si ipo ẹlẹgẹ. Lẹhin igbati o tun ṣe ọpọlọpọ iṣẹ ninu agbami okun ati ni etikun, a yan gẹgẹbi adari agba ọkọ omi ologun "Whelp". Nigbati ogun pari, o wa ni agbamiokun ilẹ Japan, o si jẹ ọkan ninu awọn ti wọn wa nibi imulẹ ti awọn ara Japan fi da ọwọ silẹ ni ilu Tokyo.

AṢẸ KINNI TI O GBA

Ọmọ'ba Philip gẹgẹbi a se mọọ ni akoko yi, di ọrẹ iyawo rẹ ni ẹni ọdun mẹtadilogun gẹgẹbi ọmọ ogun ti o mọ ẹkọ ni ile-wo ologun. Bi ọdun mẹsan sẹhin ni wọn kede igbeyawo wọn. Ninu igbeyawo ti wọn si ṣe ni ogunjọ oṣu merin ti o tẹle ikede yi, aiye gbọ, ọrun mọ, awọn enia olokiki kakiri gbogbo aiye ni ni o si lọ sibẹ.

Lẹhin igbeyawo yi o tun tẹ siwaju gẹgẹbi atukọ ninu ọkọ oju omi, bi o ti nṣiṣẹ yi ni o si tun nkọ ẹkọ ni ile ẹkọ ologun. Ko ju ọdun marun nisisiyi ti o layọ julọ gẹgẹbi atukọ, nigbati wọn yan gẹgẹbi alaṣẹ ati oludari ọkọ oju omi ilẹ Gẹsi ti a npe ni Magpie. Nigbati o gba aṣẹ yi ni o kọ iwe ti o sọ ọ di olokiki gẹgẹbi ọjọgbọn, alawada ati ẹniti ọrọ kii ba ni abo.

Awọn ọjọgbọn t o nṣe awari nipa ijinlẹ ẹkọ aiye ni ilẹ Gẹsi ti yan bi ẹgbẹ wọn. Ọrọ ti oko yi ni o wa ka ni ọjọ ti o gba ipo yi. Nibi gbogbo ni wọn si ti npokiki ọrọ yi ti o fi di oni oloni.

IṢẸ RẸ NI ARIN AWỌN ỌDỌ

Gẹgẹbi iwa awọn a tokọ oloye yi fẹran lati ma lọ si ilu ajeji ki o le ma pade awọn enia miran. Aniyan rẹ fun awọn oniruru enia ti o nba pade si ma jẹ iwuri fun ọpọlọpọ enia. O fẹran pataki julọ iṣe to ba jẹmọ ilọsiwaju awọn ọdọ.

Inu didun ti o ma nni nigbagbogbo, pẹlu ọgbọn rẹ mu ki o ku fun iṣẹ lile. O jẹ baba ẹgbẹ fun ọpọlọpọ ẹgbẹ ti o wa fun ilọsiwaju ni ilẹ Gẹsi O ti ṣe ọpọlọpọ ajo ibẹwo lọ pẹlu aya rẹ, ati ki o to di olumọran ọba Obinrin ilẹ Gẹsi pẹlu. Opọlọpọ irin ajo ni o si ti ṣe kakiri aiye lati ma wo ilọsiwaju ati awari oniruru iṣẹ kakiri. ko ni akoko pupọ fun awọn ere ti o fẹran ju ṣugbọn ko le ṣe alaimọ gba "Polo" ati Cricket", eyi ni o si ma ndari ọkọ ofurufu rẹ. Ẹ jẹki awa wo o bi o ti ṣe le ti lara oloye yi nigbati aya rẹ gun ori itẹ ti o si ni lati pa iṣẹ wonyi ti, Ṣugbọn o nṣe iṣẹ ribiribi larin awọn enia ilẹ Gẹsi, eyi si nfun ni ọpọlọpọ ayọ. Igbagbogbo ni awọn enia wọnyi si nma fi ifẹ han fun ọla ati imọran dada ti o nfun Ọba, wọn, ẹniti o jẹ iyawo rẹ. igbagbogbo ni isi ma pa iṣẹ rẹ ti lati ran Ọba Obinrin yi ọwọ ninu eto ijọba rẹ.


Mo Gbadun Siga Pirate






PIRATE

Je Siga To Dara



**Kere o!**

A ti ni orisirisi ogun Germany to ṣeṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7, Everton Road, Lagos.



Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe


## Agbako la L'eyi!

AKURE.-A gbọ jugbanu robin ti a gbọ nipe ni ọjọ Jimọ (Friday) tokọja, Mọto al'ero meji f'ori sọ arawọn lọ'na Egosi Ekii si Ọyẹ Ekiti awọn enia merinlelọgbọn ni a gbọ wipe wọn ku sinu jamba Mọto ti o ṣelẹ na ati pe ọpọlọpọ enia l'o fara pa pupọ ti wọn ko lọ si ile iwosan (Hospital) ni Akurẹ.

A gbọ wipe ile iwosan tuntun ti ọkunrin ati Ile-Iwosan ti lailai ti awọn obinrin, mejeji ni okun ekunya fun awọn to fi rapa, ọpọlọpọ lo wa larin iye ati iku Enmọ nla ni eyi jẹ fun awọn Ondo ati Agbegbe rẹ papa fun awọn Ekiti gbogbo-yiya ni awọn enia nya wọ'lu Akure lati wa mọ awọn enia ti se agbako ninu jamba Mọ'o na.

A gbọ wipe ọmọ ilewe meje obinrin aboyun, ọkọ ati iyawo, baba ati ọmọ ni awọn enia ti a gbọ pe jamba mọto na sọ d'ero ọrun alakeji arẹmabọ

Orukọ awọn enia ti a gbọ wipe wọn ku si iṣẹlẹ buburu yi ni a kọ diẹ ninu wọn; Iyafin Iyadunni Karimu ni aboyun ninu wọn baba ati ọmọ rẹ, David Longẹ ati Abraham Longẹ ọkọ ati iyawo rẹ, Olomi Ologun ati Ibitoye Ologun awọn yoku ni Jacob Bamgaye, Sule Adejare, Ojo Oniyelu Joseph Ogunleye Ayeni Ademiluwa Michael Oke, Bamji Seriki, Richard Ojo, Samuel Ọmọlọla, William Folakẹ Wura Adeṣoro, Fabicia Ipinlọmọ ati Iyalode Akodu.

Gbogbo awọn to farapa to wa ninu ile Iwosan mejeji nilu Akurẹ jẹ mẹtadin ogun, enia marun ninu wọn ni a gbọ wipe o ṣi lori ewu. Awọn to farapa pupọju ni A fa Ṣọṣi Aladura ni Ṣọṣi Ikere, manuel Ọbadare Muniratu Momọ ti Ikarẹ ati Ayinyẹmi gunjobi ti Ado Ekiti.

Enia nṣoṣo ni a gbọ wipe o la ninu awọn enia to wọ Mọto na, oluwarẹ ni ẹniti o duro lọdọ ọrẹ rẹ ni Ilu Ọyẹ ti ko wọ mọto de ibiti mọto ti ṣe ẹṣẹ.


**Now Available**

BUGLES, BEDSTEADS PAINTS, DISTEMPERS, SAFES Etc.
Just Write, Call Or Phone 21372

IKORODU TRADING COMPANY
20/28 BALOGUN STREET (P. O. BOX 395) LAGOS.
AND
NEW COURT ROAD, IBADAN

## E toju re fun ohun itan ola

Enyin omo ilewe, gbogbo nyin ni Oba Obinrin fun ni Medal lati ma fi se iranti ojo ti Oba ilu Oyinbo wa sile Nigeria. Iye medal ti Oba yi ranse fun je 38,000. Ninu gbogbo eyi 3,000 ni yio koko de lati pin fun awon omo ilewe ni Eko.

Awon ti o ba sorire lati gba Medal na, ki o lo fi pamo nitori ki o le ri okan fi pitan fun awon omo re wipe, lasiko bayi-bayi nigbati iwo koiti de aiye ti Oba Obinrin ilu Oyinbo wa sile yi ti mo si foju ri i, Medal ti o fun wa lojo na niyi.


## Irora Ni Orike ikeHti Isan Ara
BIYA ARUN IGBAROKO LOFA

Ise ti KIDINRIN tabi olo-inu nse ni lati ko gbogbo idoti ti o mbe ni ara danu, Bi awon Kidinrin nwonyi ko ba lise daradara awon idoti ara na yio ma po si, yio si wa di irora fun enia ni orikerike ninu ara.

Ona ti a le gba fi ba gbogbo arun yi ja ni wipe ki a se iranlowo fun Kidinrin lati sise re egbogi ti a npe ni DE WITT'S yi lo le sise na.

Nitori iru arun bayi ni a sese egbogi na o si je atura o si nfo inu enia mo nipa jije ki Kidinrin bere ise.

A ti dan egbogi DE WITT'S yi wo a si ri wipe o dara, Kakiri gbogbo agbaiye ni a nta Opolopo iwe ni a ti ri gba lati odo awon ti arun yi mba ja, ti awon si ti ri iwosan kiakia.



Kini nda o duro ti iwo ko danwo fun irora tire ki o si sobu egbogi lo ra okan wo.

Egbogi DE WITT'S dara fun Ehin didun, Irora Orike Laku rogbe Igbaroko ati arun Isan ara.

Ohun ti o dawa loju nipe egbogi DE WITT'S yi je oyitl a se tonitoni gbogbo egbogi o si dara.




**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles




Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ogbeni Olola S.O. Awokoya ti o nse Olotu Eko, O ti si ile ise akowe kan sile ni ile ise ijoba (Secretariat) ni Ibadan nibiti ao ti ma fesi awon egberun meta iwe fun Scholarship.

## MINISTRY OF EDUCATION WESTERN REGION

### REGISTRATION OF PRIVATE INSTITUTIONS.

**Sect. 38 of the W.R Education Law. 1954.**

The Commercial Schools named below have been registered as private institutions by the Registrar of private institutions appointed by the Minister of Education in accordance with Section 38 (1) of the Western Region Education Law:-

1. St. James's Secretarial School, Oke-Ado. Ibadan
2. MacJob School of Commerce, Abeokuta.
3. Ebenezer School of Commerce, Ibadan
4. Payne's Vocational Tutorial College, Oniyanrin, Ibadan
5. Mercantile Training School, Oke-Ado, Ibadan
6. New Oxford College, Benin City
7. Ibadan Commercial School, Oke-Ado. Ibadan
8. United College of Commerce, Igbodu, Warri
9. Abeokuta Boys' Commercial School Lafenwa Abeokuta
10. Lisabi Commercial School, Ijeko, Abeokuta
11. Niger College, Benin City
12. Western School of Commerce, Aperin, Ibadan
13. Owo Commercial School, Owo.

2. It should be noted for public information that:-
   (1) Registration does not imply approval.
   (2) No Commercial School in the Western Region is, at present, approved by the Ministry of Education.
   (3) No commercial School in the Western Region is, at present, in receipt of Government grant-in-aid.
   (4) Internal Certificates of the above named institutions are not recognized by Government.

3. The attention of proprietors of Commercial Schools in the Western Region, which were in existence before 1954 and which are not named above, is directed to Western Regional Notice No. 295 in Gazette No 20 of 5/5/55, and to Section 42 (2) of the Education Law 1954.


## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**
*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

